**7.** Nitorina nigbati o ba bùṣe ki o gbiyanju.

فَإِذَا فَرَغْتَ فَانصَبْ ٧

**8.** Nitorina ṣe ojukòkòrò lọ si ọ̀dọ̀ Oluwa rẹ̀.

وَإِلَىٰ رَبِّكَ فَارْغَب ٨

## *(95) Suratul - Tini*

## سُورَةُ التِّينِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Mo fi eso ọpọtọ (Tini) bura ati eso igielepo didun.

وَالتِّينِ وَالزَّيْتُونِ ١

**2.** Ati oke 'Sĩnĩna' (bura).

وَطُورِ سِينِينَ ٢

**3.** Ati ilu ifaiyàbalẹ yi (bura).

وَهَٰذَا الْبَلَدِ الْأَمِينِ ٣

**4.** Dajudaju A da enia ni ẹ̀yà daradara julọ.

لَقَدْ خَلَقْنَا الْإِنسَانَ فِي أَحْسَنِ تَقْوِيمٍ ٤

**5.** Lẹhinna A o da a pada si àyè ti o rẹlẹ̀ jù.

ثُمَّ رَدَدْنَاهُ أَسْفَلَ سَافِلِينَ ٥

**6.** Ayafi awọn ti o gbagbọ ni ododo ti o si nhuwa rere; nitorina ẹsan ti kò ni ja mbẹ fun wọn.

إِلَّا الَّذِينَ آمَنُوا وَعَمِلُوا الصَّالِحَاتِ فَلَهُمْ أَجْرٌ
غَيْرُ مَمْنُونٍ ٦

**7.** Atipe tani ẹni ti otun le pe ọ lopurọ (irẹ Annabi) nipa idajọ Ọlọhun tabi isiro lẹhinna?

فَمَا يُكَذِّبُكَ بَعْدُ بِالدِّينِ ٧

**8.** Njẹ ki iṣe Ọlọhun ni O mọ ẹjọ da ju gbogbo oludajọ lọ bi?

أَلَيْسَ اللَّهُ بِأَحْكَمِ الْحَاكِمِينَ ٨